# ỌDUN JUBELI
## Lefitiku 25:1-46
### ẸKỌ 89 – FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "OLUWA mọ̀ ọjọ ẹni iduro-ṣinṣin: ati ilẹ-ini wọn yio wà lailai" (Orin Dafidi 37:18).**

**A Ṣe Ileri Kenaani**

Ọlọrun ti ṣe ileri fun Abrahamu, ni ọpọlọpọ ọdun ṣiwaju ijade lọ awọn Ọmọ Israẹli kuro ni Egipti, pe Oun yoo fi ilẹ iyanu fun awọn ọmọ Abrahamu lati maa gbé. Awọn ile yoo ti wà ni kikọ́ fun wọn, awọn ajara yoo ti wà ni gbigbìn, awọn igi yoo maa so eso (Deuteronomi 6:10, 11). Ohun ti wọn yoo ṣe ko ju pe ki wọn kan wọ ibẹ̀ -- bi wọn ba gbọran si Ọlọrun lẹnu. Ni tootọ wọn o lé awọn keferi ti n gbé ibẹ̀ jade – ninu wọn si jẹ́ òmìrán -- ṣugbọn Ọlọrun ti ṣe ileri lati lọ ṣaaju ati lati ja ogun wọn fun wọn bi wọn ba gbọran si I.

Awọn Ọmọ Israẹli ni ọmọ Abrahamu, ni iran-iran pupọ lẹyin igba ayé rẹ̀. Nigba ti wọn jade kuro ni Egipti wọn bẹrẹ irin-ajo wọn si Kenaani lati gba ilẹ ti Ọlọrun ti ṣe ileri. Ṣugbọn wọn ni ẹ̀kọ́ pupọ lati kọ́ ki wọn to de ibẹ.

Ẹkọ kan ti Ọlọrun fẹ kọ́ awọn Ọmọ Israẹli ni lati ni inu rere ati ẹmi ibakẹdun fun ọmọnikeji wọn. Oun kò fẹ ki wọn kan jẹ́ ọlọrọ ki wọn si ni gbogbo ilẹ naa, ki awọn miiran si jẹ́ talaka ti yoo ṣe ẹru awọn ọlọrọ. Bi awọn kan ba di alaini ti wọn ba si ni lati ṣiṣẹ fun ẹlomiran, ẹni ti wọn n ṣiṣẹ fun ni lati ṣe iyọ́nú si wọn, ki o si ranti pe wọn ti jọ ṣe ẹru rí ni Egipti. Bi ko ba ṣe pe Ọlọrun ti ṣaanu fun wọn ti O si ti yọ wọn kuro ninu isinru, gbogbo wọn ni i ba jẹ ẹru sibẹ. Ọlọrun fẹ ki wọn dupẹ fun ominira wọn ki wọn si bá ara wọn lò bi ominira, ọmọ Oluwa.

**A Pín Ilẹ̀ Naa**

Nigba ti awọn Ọmọ Israẹli wọ Kenaani, Ọlọrun pín ilẹ naa ki ẹya kọọkan ba le ni ipin ti o tọ́. O fẹ ki wọn jọwọ ipinlẹ kọọkan si ikawọ ẹ̀ya ti Oun ti yan an fun. Wọn kò ṣiṣẹ lati ni ilẹ; wọn ko ni owo ti wọn i ba san fun un; ẹbun Ọlọrun ni.

Ohun gbogbo ti a ní, lati ọdọ Ọlọrun wá ni, a si ni lati dupẹ lọwọ Rẹ̀ fun un. Nigba ti a ba jokoo lati jẹ ounjẹ a ni lati kọ́ dupẹ lọwọ Oluwa pe O fun wa ni ounjẹ lati jẹ. Nigba ti a ba lọ sun ni alẹ a o yin In fun ibugbe ati fun ibusun ti a ni fun sísùn. Nigba ti a ba jí lowurọ a gbọdọ yin In fun isinmi ti O ti fun wa, ati fun aṣọ ti a n wọ̀. A o tun beere pe ki O fun wa ni ounjẹ oojọ wa, Oun yoo si ṣe e. Nigba ti a ba fi hàn An pe ohun ti O ṣe fun wa jọ wa loju, inu Rẹ̀ yoo dùn lati fun wa si i.

**Ọjọ Isinmi**

Nigba ti awọn Ọmọ Israẹli bẹrẹ irin-ajo wọn lọ si Kenaani, Ọlọrun sọ fun wọn lati maa sinmi ni ọjọ keje. Ọjọ yii ni wọn n pè ni Ọjọ Isinmi. Ọlọrun bọ́ awọn eniyan naa nipa rirán manna ti wọn n kó lori ilẹ ni oroowurọ afi ni Ọjọ Isinmi. Ni ọjọ kẹfa manna pọ̀ ni ilẹ to eyi ti wọn le kó jọ fun ọjọ meji - ko si ni bajẹ bi o ti n ṣe ni ọjọ miiran nigba ti wọn ba kó ju eyi ti wọn n fẹ lọ fun ọjọ naa. Ọlọrun ti wi fun awọn eniyan naa pe wọn ni lati ya Ọjọ Isinmi si mimọ́, O si fi ṣe dandan pe wọn kò gbọdọ ṣe iṣẹkiṣẹ ni ọjọ naa.

Nigba ti wọn ba de ilẹ Kenaani, ilẹ naa ni lati ni Isinmi. Ilẹ ti o dara pupọ ni, Ọlọrun si n fẹ ki wọn boju to o. Ni ọdun keje wọn kò gbọdọ gbin irugbin kankan, ki ilẹ na ba le sinmi. Ki i rẹ ilẹ bi o ti n rẹ eniyan, ṣugbọn nigba ti a ba n gbin nnkan lọdọọdun awọn irugbin naa a maa mu ounjẹ pupọ kuro ninu ilẹ to bẹẹ ti o fi jẹ pe lẹyin igba diẹ ilẹ naa yoo "di ṣiṣá". Bi awọn eniyan kò ba ni nnkan ti a fi n mu ilẹ lọra (ajilẹ) ilẹ yoo sọ ara rẹ̀ di ọtun bi a ba jẹ ki o sinmi fun ọdun kan.

Yatọ si titọju ilẹ, Ọlọrun fẹ kọ́ wọn lẹkọọ siwaju si i pe Oun yoo bọ́ awọn ọmọ ti Oun. O ṣeleri pe ni ọdun kẹfa eso wọn yoo pọ̀ to bẹẹ ti ounjẹ yoo fi wà lọpọlọpọ fun ọdun Isinmi. Awọn nnkan ti o ba hù ni ọdun naa lai jẹ pe wọn gbin in ni wọn ni lati fi silẹ fun awọn talaka ati awọn ẹranko (Ẹksodu 23:11).

Ọlọrun kò ni jẹ ki ebi pa awọn ọmọ Rẹ̀. Ileri Rẹ̀ fun awọn olododo ni pe: "On na yio gbe ni ibi giga: ilẹ apáta yio ṣe ibi ãbo rẹ, a o fi onjẹ fun u; omi rẹ yio si daju" (Isaiah 33:6). Dafidi kọ ninu Saamu rẹ̀ kan, "Emi ti wà li ewe, emi si dagba; emi ko ti iri ki a kọ̀ olododo silẹ, tabi ki iru-ọmọ rẹ ki o ma ṣagbe onjẹ" (Orin Dafidi 37:25). Fun gbogbo ogoji ọdun ti awọn Ọmọ Israẹli lò ni aginju Ọlọrun fun wọn ni manna jẹ. O yẹ ki wọn ti gbagbọ nigba gbogbo pe Ọlọrun yoo tọju wọn daradara Oun kò si ni jẹ ki ebi pa wọn.

Ọlọrun n fẹ ki awọn eniyan Rẹ̀ lonii gbẹkẹle Oun, ki wọn má si ṣe ṣaniyan ki ni wọn o jẹ tabi ki ni wọn o fi bora. Jesu wi fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ nigba ti O wà ni ayé pe, "Ologoṣẹ marun ki a ntà li owo idẹ wẹ́wẹ meji? a kò si gbagbé ọkan ninu wọn niwaju Ọlọrun? (Luku 12:6). Bi Ọlọrun ba n ṣe itọju awọn ẹyẹ keekeekee, kò ha ni ṣe itọju awọn ọmọ Rẹ̀ pẹlu?

**Ọdun Jubeli**

Lẹyin ọdun meje meje ọna meje bayii, eyi ni pe lẹyin ọdun mọkandinlaadọta, ọdun isinmi kan tun wà. Eyi ni wọn pè ni ọdun Jubeli, tabi ọdun ominira, tabi idasilẹ. Nṣe ni o tẹle ọdun Isinmi kan gan an, o wá di ọdun meji leralera ninu eyi ti wọn kò gbin ohunkohun. Ṣugbọn Ọlọrun a maa ṣe abojuto ohun gbogbo, O si ṣe ileri fun wọn pe wọn yoo ni ọkà ati ewebẹ ati eso ni ọdun kẹfa eyi ti ki yoo tán ni ọdun keje ati kejọ, ani titi di igba ikore ti ọdun kẹsan-an.

Ni Ọjọ Etutu ti ọdun Jubeli, wọn fun ipè kikan kikan. Ọjọ naa jẹ ọjọ ironu ninu eyi ti awọn eniyan naa ranti ẹ̀ṣẹ wọn. Ṣugbọn nigba ti wọn ba ti ṣe gbogbo irubọ tán gẹgẹ bi Ọlọrun ti pa laṣẹ, awọn eniyan naa a yọ̀ gidigidi. Nigba

ti wọn ba si gbọ́ iro ipe, eyi ti, gẹgẹ bi àṣa, jẹ akoko gan an fun idasilẹ awọn iranṣẹ ati imupadà ohun ini, inu wọn a dùn lọpọlọpọ.

Ni ọdun idasilẹ yii, ẹnikẹni ti o ba ti ta ninu ilẹ rẹ̀ laaarin ọdun mọkandinlaadọta ti o kọja ni o le gba a pada lọfẹẹ. Bi ẹnikẹni ba ti di alaini to bẹẹ ti o fi ni lati fi ara rẹ̀ sọfa lati maa ṣiṣẹ fun ẹlomiran o le lọ si ile rẹ lọfẹẹ nisisiyii. Ro bi inu gbogbo awọn eniyan naa yoo ti dùn tó nigba ti gbese wọn ba ti di igbagbe ti wọn si le jẹ igbadun ogun-ibi wọn bi wọn ti n ṣe ki wọn to di alaini!

Ọlọrun kò fẹ ki awọn awọn ọlọrọ fi iyà jẹ awọn alaini, ṣugbọn bakan naa ni Oun ko fẹ ki awọn talaka rẹ́ awọn ọlọrọ jẹ. Bi wọn ba ta ilẹ naa ni ọpọ ọdun ṣaaju ọdun Jubeli, wọn le fi owo nla le e, ṣugbọn bi ko ba ju ọdun meji tabi mẹta ṣaaju Jubeli wọn ko le beere ju iye owo ti o tọ́ si ilẹ naa fun akoko ti o kù. A le wi pe ilẹ naa wà fun fifi sọfa dipo tita gan an nitori olukuluku ni lati dá ilẹ ti o ti rà pada ni aadọta ọdun (Jubeli).

**Rirapada Ṣaaju Jubeli**

Nigbakuugba ti wọn ba ta ilẹ, wọn a ṣe iwe ẹri meji. Ọkan, ninu eyi ti iye owo rira ilẹ naa wà, ni wọn fi edidi di ti wọn si fi si ibi ipamọ kan. Ekeji wà ni ṣíṣí a si maa bá ohun ini naa lọ nigbakuugba ti o ba ti ọwọ́ ẹni kan bọ́ si ọwọ́ ẹlomiran. Bi ẹni kan lati idile kan naa pẹlu ẹni ti o ti ni ilẹ naa tẹlẹ ri ba fẹ lati ra ilẹ naa pada fun awọn eniyan rẹ̀, o le ṣí iwe-ẹri ti a fi edidi dí, ki o si wo iye owo rẹ̀, ki o si ra a pada ṣaaju ọdun Jubeli. Eyi ni a n pe ni rira ilẹ naa pada, ẹni ti o ba si rà a ni olurapada.

Ninu iwe Rutu a ri apẹẹrẹ ibatan kan ti o ra ilẹ pada. Naomi, ọkọ rẹ̀ Elimeleki, ati awọn ọmọkunrin rẹ̀ meji di talaka gidigidi nitori iyàn kan ni ilẹ Juda, wọn si lọ si ilu miiran lati maa gbé. Ni ọdun pupọ lẹyin naa, lẹyin ti awọn ọmọkunrin rẹ̀ mejeeji ti gbeyawo ti wọn si ti kú, ti ọkọ rẹ̀ si ti kú pẹlu, Naomi pinnu lati pada si ilu oun tikara rẹ̀. Rutu ọkan ninu awọn aya-ọmọ rẹ̀, pada pẹlu rẹ̀. Wọ́n jẹ́ alaini sibẹ, ominu si n kọ́ wọn pe boya ibatan kan yoo wà ti yoo le ra ilẹ wọn pada fun wọn. Rutu tọ Boasi lọ, ọlọrọ kan ti i ṣe ti idile Elimeleki, o si sọ fun un nipa ohun ti o de ba wọn, ki o le mọ̀ bi yoo ba le ra ilẹ wọn pada. Boasi pinnu lati ṣe "iṣe ibatan" bi ọkunrin miiran ti i ṣe ibatan ti o sún mọ́ wọn ju oun lọ kò ba fẹ ṣe bẹẹ. Ọkunrin keji yọọda ẹtọ rẹ̀ fun Boasi lati ra ilẹ naa pada nipa bibọ bata rẹ̀ fun Boasi, gẹgẹ bi iṣe wọn nigba naa. Nitori naa Boasi ra ilẹ naa ti o ti jẹ ti Elimeleki tẹlẹ ri, o si fẹ́ Rutu ni aya. Ọmọ-ọmọ-ọmọ wọn ni Dafidi ọba, ẹni ti o kọ ọpọlọpọ ninu awọn Saamu inu Bibeli. Ni ọpọlọpọ iran lẹyin naa ni a bí Jesu sinu idile wọn.

**Olurapada Wa**

Jesu ni Olurapada wa. Gẹgẹ bi ẹlẹṣẹ a ta ara wa fun Satani a kò si ni nnkan kan ti a le fi ra ominira wa. Jesu wá lati wẹ gbogbo ẹ̀ṣẹ wa ati lati já agbara ọta kuro ninu ayé wa, lati tun ṣọ wa di ominira. O ṣe iṣe ibatan" fun wa. Oun ni Ẹni kan ṣoṣo ti O jẹ san owo irapada wa, O si ti fi Ẹjẹ ti Rẹ̀ san an.

**Ọdún Itẹwọgba Oluwa**

Ninu ọ̀kan lara iwaasu ti Jesu kọkọ ṣe, O kà ninu awọn ẹsẹ ọrọ asọtẹlẹ ti Isaiah ti sọ nipa Rẹ̀ ni ọpọlọpọ ọdun sẹyin. "Ẹmi Oluwa mbẹ lara mi, nitoriti o fi àmi ororo yàn mi lati wasu ihinrere fun awọn otoṣi; o ti rán mi wá lati ṣe iwosan awọn ọkàn onirobinujẹ, lati wasu idasilẹ fun awọn igbekun, itunriran fun awọn afọju, ati lati jọwọ awọn ti a palara lọwọ, lati kede ọdún itẹwọgba Oluwa" (Luku 4:18, 19). "Ọdún itẹwọgba Oluwa" naa ni ọdun Jubeli ti ẹmi eyi ti yoo fun awọn ẹlẹṣẹ ti o ronupiwada ni idaniloju idasilẹ kuro ninu idè ẹ̀ṣẹ, eyi ti yoo mú ki ara awọn olokunrun di dídá, eyi ti yoo mu ki olukuluku ẹni ti o ba gba Jesu gbọ́ layọ. Nigba ti Jesu ti ka awọn ẹsẹ ọrọ wọnyii, O jokoo O si wi pe, "Loni ni Iwe-mimọ yi ṣẹ li etí nyin" (Luku 4:21). Mimu idariji wá fun ẹṣẹ, alaafia fun ọkàn ti o poruuru, iriran fun oju ti o fọ́, ṣe pataki ju idapada ilẹ ti a ti tà. A le gba ominira yii sibẹ nipasẹ Jesu bi a ba tọ̀ Ọ́ wá pẹlu ironupiwada, ti a si bẹ̀bẹ̀ pe ki O dari ẹ̀ṣẹ wa jì wá. A le jẹ anfaani "ọdun idasilẹ" wa lonii nipa Ẹjẹ Jesu.

Bi ipe ti dun ni Ọjọ Etutu ti ọdun Jubeli, bẹẹ naa ni Johannu Baptisti de ti o si kede wiwá Jesu si ayé. Apa kan ikede rẹ̀ ni, "Gbogbo ọgbun li a o kún, gbogbo òke nla ati òke kekere li a o tẹ-bẹrẹ, wíwọ li a o ṣe ni títọ, ati ọ̀na palapala li a o sọ di kikuna" (Luku 3:5). Eyi ki i ṣe pe awọn oke nla yoo kuku yọ́ sinu awọn ọgbun lati mu ki ilẹ tẹ́ pẹrẹṣẹ; eyi tumọ si pe Jesu yoo tun mu ohun gbogbo dọgba bi ti igba ọdun Jubeli nigba ti olukuluku pada si ilẹ-ini rẹ̀. Eyi kò sọ nipa ilẹ biri ti ẹni kọọkan ni lati ni, bi ko ṣe pe olukuluku eniyan ni o le ni ilẹ-ini ti ẹmi ninu Jesu, ọlọrọ ati talaka le ri igbala lọna kan naa.

**Jubeli Nla ti o n Bọ̀**

Ọdun Jubeli miiran ṣi n bọ̀ wá nigba ti Jesu "yio si rán awọn angẹli rẹ̀ ti awọn ti ohùn ipè nla, nwọn o si kó gbogbo awọn ayanfẹ rẹ̀ lati ori igun mẹrẹrin aiye jọ, lati ikangun ọrun kan lọ de ikangun keji" (Matteu 24:31). Nigba naa ni ẹgbẹrun ọdún alaafia yio bẹrẹ nigba ti Jesu yoo jẹ Ọba. Awa ti a ba mura silẹ nisisiyii fun akoko ti Jesu yoo gba awọn eniyan Rẹ̀ soke kuro ninu ayé, yoo ni anfaani iyebiye lati jọba pẹlu Rẹ̀.

**AWỌN IBEERE**

1. Ki ni ọdun Jubeli?
2. Ki ni awọn Ọmọ Israẹli yoo jẹ laaarin ọdun naa?
3. Ẹkọ wo Ọlọrun n fẹ kọ́ awọn Ọmọ Israẹli nipa ilana ọdun Isinmi ati ọdun Jubeli?
4. Ta ni le ra ilẹ pada, eyi ti a ti tà ki ọdun Jubeli to de?
5. Ta ni Olurapada wa?
6. Ewo ni "ọdún itẹwọgba Oluwa"?